**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Awọn Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (5)**

**Ijẹ́wọ́: Isaiah 53:5:** Ṣugbọn a ṣa a ni ọgbẹ́ nitori irékọjá wa, a pa a lara nitori aiṣedede wa; ina àláfíà wa wa lara rẹ, ati nipa iná rẹ ni a fi mu wa lara da.

## Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn

1. Ọlọ́run gbogbo ẹran ara, wo mi san ni ibi gbogbo ti mo ti nilo ìwòsàn, ní orúkọ Jésù.
2. Mo paṣẹ imupada-bọ-sipo ati ìwòsàn pipe si gbogbo agbegbe ayé mi, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run imupada-bọ-sipo, parọ ninu mi, ohunkohun ti o nilo iparọ ninu ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Mo fọ gbogbo ìdè òkùnkùn si ilana búburú iyowu, ní orúkọ Jésù.
5. Ọlọ́run àtúnṣe, ṣe àtúnṣe ninu mi, ohunkohun ti o nilo àtúnṣe, ní orúkọ Jésù.
6. Mo tu ara mi silẹ̀ kuro ninu ègún irora ati òṣì, ní orúkọ Jésù.
7. Mo fa a lulẹ, ibi giga iyowu ti wọn kọ sinu ayé mi lati ọwọ́ alagbatọ mi nigbati mo wa ni ikókó, ní orúkọ Jésù.
8. Mo faa lulẹ, gbogbo ibi giga ifiji búburú ti wọn yan lati ba àyànmọ́ mi jẹ, ní orúkọ Jésù.
9. Mo tu ara mi silẹ kuro lọwọ ẹ̀mí ipadasẹyin, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo gbolohun ibi ti wọn sọ lodi si itẹsiwaju mi, gba ifagile, ní orúkọ Jésù.
11. Mo ke ara mi danu kuro lọwọ àwọn ẹmi agbègbè, ní orúkọ Jésù.

12. Mo ba gbogbo ajẹnirun ti wọn so pọ mọ ètò iṣuna owó mi wi, ní orúkọ Jésù.

13. Nibo ni Olúwa, Ọlọ́run Elijah wa? Dide, ki O si jẹ ki iná Rẹ jo gbogbo òkùnkùn ni gbogbo agbègbè ayé mi, ní orúkọ Jésù.

14. Mo tu ara mi silẹ kuro ninu igbekun iṣẹ takuntakun ti ko lere, ní orúkọ Jésù.

15. Olúwa, jẹ ki gbogbo iwadi òkùnkùn nipa ayé mi maa di asán ati òfò, ní orúkọ Jésù.

16. Ẹṣẹ iyowu ti mbẹ ninu ayé mi ti nmu aisan ba mi, ku, ní orúkọ Jésù.

17. Ina Ẹmi Mimọ, fọ ipilẹ ayé mi mọ, ní orúkọ Jésù.

18. Olúwa, jẹ ki agbara ìsọjí ba le ara, ọkàn ati ẹ̀mí mi, ní orúkọ Jésù.

19. Gbogbo ounjẹ buburu ti nko aisan ba àgọ́ ara mi, jade ki o si ku, ní orúkọ Jésù.

20. Gbogbo ègún ti npọn àyànmọ́ mi loju, fọ nipa ẹ̀jẹ̀ Jesu, ní orúkọ Jésù.

21. Gbogbo gbongbo ipọ́njú ninu ayé mi, gbẹ danu nipa iná, ní orúkọ Jésù.